**IGBESI-AYÉ IWA MIMỌ́**

**1 Peteru 1:1-25; 2:1-25**

**ẸKỌ 452 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ṣugbọn gẹgẹ bi Ẹni ti o pè nyin ti jẹ mimọ́, bẹ̃ni ki ẹnyin na si jẹ mimọ́ ninu iwa nyin gbogbo: nitori a ti kọ ọ pe, Ẹ jẹ mimọ́; nitoriti emi jẹ mimọ́" (1 Peteru 1:15, 16).**

**I Ọrọ Itunu Peteru**

1 A ni ireti aaye nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu okú, 1 Peteru 1:1-3; 1 Kọrinti 15:20

2 A fi ogún aidibajẹ silẹ de wá ni Ọrun 1 Peteru 1:4, 5; Kolose 1:5; 2 Timoteu 4:8

3 Bi a tilẹ n dán igbagbọ́ wa wò, o ni iye lori ju wura lọ, 1 Peteru 1:6-9; Jobu 23:10; Orin Dafidi 66:10; Jakọbu 1:3

4 Igbala jẹ ohun ti awọn wolii ati awọn angẹli ni ifẹ́ sí gidigidi, 1 Peteru 1:10-14; Ẹksodu 25:18-20; Efesu 3:9, 10

5. Mimọ́ ni Ọlọrun. Awa ọmọ Rẹ̀ si gbọdọ ni aworan Rẹ̀, 1 Peteru 1:15-17; Lefitiku 11:44; Luku 1:74, 75; Heberu 12:14

6 A ko fi ohun ti i dibajẹ ra wa pada, 1 Peteru 1:18-21; Iṣe Awọn Apọsteli 20:28; Efesu 1:7; Heberu 9:12-14; Ifihan 5:9

**II Imọran Peteru**

1 Ẹ fẹ́ ọmọnikeji yin gidigidi lati inu ọkàn mimọ́ wa, 1 Peteru 1:22-25; Romu 12:9, 10; 1 Timoteu 1:5; 1 Johannu 3:18

2 Ẹ fi ohun gbogbo ti i ṣe ibi silẹ ki ẹ si ṣe afẹri wara Ọrọ naa ti kò ni ẹtan, 1 Peteru 2:1-3, 11, 12; Matteu 18:3; 1 Kọrinti 3:2; Efesu 4:22-25; Kolosse 3:8; Heberu 12:1; Jakọbu 1:21

3 Kristi, "Okuta ãye", ti o ṣe iyebiye fun awọn Onigbagbọ́, ṣugbọn "okuta idigbolu" fun awọn alaigbọran, 1 Peteru 2:4-12; Efesu 2:19-22

4 Awọn Onigbagbọ́ gbọdọ gbọran si awọn alaṣẹ ilu lẹnu, gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun, 1 Peteru 2:13-17; Matteu 22:21; Romu 13:1

5 Awọn ọmọ-ọdọ ni lati tẹriba fun awọn oluwa wọn, 1 Peteru 2:18-23; Efesu 6:5-8; Kolosse 3:22-25; 1 Timoteu 6:1; Titu 2:9, 10

6 Wọn ti ṣako lọ bi agutan, ṣugbọn nisisiyii wọ́n pada si ọdọ Oluṣọ-agutan wọn, 1 Peteru 2:24, 25; Isaiah 53:6; Esekiẹli 34:6; Johannu 10:11-16.

## ALAYE

### Ọrọ Iṣaaju Peteru

A lero pe a kọ Episteli yii ni gẹrẹ lẹyin ikú-ajẹriku Paulu. Awọn ijọ ti Paulu ti dá silẹ n la "idanwò iná" kọja. O to nnkan bi ogoji ọdun o din marun-un lẹyin Pẹntikọsti, a si n ṣe inunibini lile si ijọ Ọlọrun. Ni ireti boya lati bo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ, Nero ti i ṣe Alakoso ilu Romu, n fi ẹsun jijó ilu Romu kan awọn Onigbagbọ́.

Peteru n kọ iwe yii lati rú igbagbọ́ awọn eniyan mimọ́ wọnyii soke. Boya oun paapaa ti bẹ awọn ijọ ti a darukọ wọn ni ibẹrẹ Ẹpisteli yii wò, ti o si mọ pupọ ninu awọn eniyan mimọ́ wọnyii lojukoju; a le mọ bi yoo ti jẹ inudidùn wọn lati ri iwe yii gbà lati ọdọ Peteru. O n ti ọwọ Sila, ti i ṣe ọ̀kan ninu awọn alabaṣiṣẹpọ pẹlu Paulu ninu Ihinrere, fi ranṣẹ si wọn. O le jẹ pe Sila n bẹ awọn ijọ wọnyii wò lati fun wọn ni iroyin ikú Paulu.

**Titobi Ihinrere**

Peteru n fẹ ki awọn eniyan mimọ́ wọnyii mọ bi igbala nla yii ti niye lori to. O tọka si bi awọn wolii ti ni ifẹ gidigidi lati wo nnkan wọnyii nigba ti wọn sọ asọtẹlẹ ijiya Kristi ati ogo ti yoo tẹle e. "Awọn ẹniti a fihàn fun, pe ki iṣe fun awọn tikara-wọn, bikoṣe fun awa ni nwọn ṣe iranṣẹ ohun wọnni, ti a ròhin fun nyin nisisiyi, lati ọdọ awọn ti o ti nwãsu ihinrere fun nyin pẹlu Ẹmi Mimọ́ ti a rán lati ọrun wá; ohun ti awọn angẹli nfẹ lati wò" (1 Peteru 1:12). O ṣe e ṣe ki o jẹ pe awọn kerubu ti o duro lapa ọtun ati osi ori Apoti majẹmu ni a n tọkasi nihin. Wọn wà ni itẹriba bi ẹni pe wọn n fẹ wo ohun ti o wà ninu Apoti naa.

Bi igbe-ara-wọ Kristi ati eto irapada Rẹ̀ nla ba jẹ ohun ti awọn angẹli Ọlọrun ni ifẹ si gidigidi, melomeloo ni o yẹ ki o mu awa pẹlu lọkàn, awa ẹni ti Kristi wá fun, ti O jiya ti O si kú ki awa ki o ba le ri idande.

"Nitorina ẹ di ọkàn nyin li amure", ẹ ṣe giri, ki ẹ si maa reti gbogbo nnkan wọnni ti Ọlọrun ti ṣe ileri ni igba ifarahàn Jesu Kristi.

**Iwa Mimọ́**

Mimọ́ ni Ọlọrun. Bi Ọlọrun ba jẹ́ Baba wa, awa ti a jẹ́ ọmọ Rẹ̀ nigba naa gbọdọ ni aworan Baba wa. Gbogbo igbesi-ayé Onigbagbọ́ ni lati jẹ mimọ́. Irin wa, isọrọ wa, igbesi-ayé wa ojoojumọ ni lati jẹ́ mimọ́. Ninu awọn ẹsẹ diẹ ti o kẹyin ninu ori kin-in-ni Iwe Peteru Kin-in-ni, ibi titun, eto irapada, ati iwa-mimọ́ ni a fi siwaju wa ni ọna ti o wu ni pupọ.

**Irapada**

Fadaka ati wura jẹ irin iyebiye ti a n lò bi ohun ipaarọ ṣugbọn bi wọn ti niyelori to ni wọn ko le rà wá pada. Ohun irapada wa niyelori lọpọlọpọ ju awọn irin wọnyii lọ.

Labẹ Ofin, bi eniyan kan nipa aini tabi ohun miiran ko ba le san gbese rẹ̀, oun ati awọn ohun ini rẹ̀ ni a n tà lati san gbese naa. Ṣugbọn Ofin fi eto irapada silẹ nipa eyi ti a fi le ra ajigbese naa pada. Ibatan ti o sun mọ ọn ju lọ le san gbese naa ki o si dá a silẹ.

Jesu gbé ẹran ara eniyan wọ̀, O di arakunrin wa agba ki Oun le ni ẹtọ lati rà wá pada si ọdọ Ọlọrun. Awọn obi wa iṣaaju tà wá fun Eṣu. Jesu fi Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye rà wá pada. Wo bi iye ti O san ti pọ̀ to lati ra wa pada si ọdọ Ọlọrun! Eyi fi hàn bi Ọlọrun ti ka ẹmi eniyan si ohun ti o ṣe iyebiye pupọ.

Pupọ eniyan ni ko ka ẹmi wọn si ohun ti o ni laari. Sihin sọhun ni wọn n ju ẹmi wọn kiri lai bikita boya o ṣegbe tabi ko ṣegbe, titi de ogbirigbiri ibi ti ko tilẹ ni si ireti fun wọn mọ́. Eṣu ti fọ́ wọn loju, o si n du u ki wọn le jẹ́ afọju titi. Ihinrere mú imọlẹ wá. Eredi ti a fi n ṣaapọn lati mu ki Ihinrere yii ki o di mimọ̀ fun ayé ti o n ṣegbe lọ ni yii.

**Arankan**

Awọn iwa buburu ti a mẹnukàn, ko ṣe deedee pẹlu ifẹ ará ti Peteru ti kọwe nipa rẹ̀. Arankan ni a kọ́ mẹnukan, iwa buburu keji si n ti inu ekinni ti a darukọ ṣiwaju jade. Lati inu arankan ni ẹtan ti n sun jade, agabagebe si n ti inu ẹtan jade, owú n ti inu agabagebe jade; ọ̀rọ buburu si n ti inu owú jade. Gbogbo wọnyii ni a n parun patapata ninu ọkàn nigba ti ifẹ ará ba n jọba nibẹ.

**Ọrọ Funfun**

Awọn ọmọ-ọwọ a maa dagba lọna ti ẹda nigba ti wọn ba n mu wara lati ara iya wọn. Awọn Onigbagbọ ti wọn ṣẹṣẹ ni iyipada ọkàn a maa dagba pẹlu nigba ti wọn ba n mu wara Ọrọ Ọlọrun tootọ. A maa mú ki igbagbọ́ dagba soke, igbagbọ́ a si maa fi ọkàn balẹ lori ipilẹ ti o daju.

Boya ko tilẹ ti i si igba naa ninu itan Ijọ Ọlọrun ti ipilẹ Ihinrere ti ni idojukọ to bi ti akoko yii. Ẹkọ eke, igbọjẹgẹ, igbesi-ayé ailakoso, aibikita fun Ọrọ Ọlọrun, ojukokoro owó ati agbara n ti ayé yii si ọna gbigbooro ti iparun.

Jesu Kristi ni ipilẹ ti ijọ sinmi le lori. Oun ni a n pè ni "Okuta ãye", Oun si ni orisun iye fun gbogbo awọn ti o gbagbọ́.

**Igbọran si Ofin**

"Ẹ mã tẹriba fun gbogbo ilana enia nitori ti Oluwa" (I Peteru 2:13). Paulu wi pe awọn alaṣẹ ti o si wà lati ọdọ Ọlọrun ni a ti ṣe ilana rẹ̀ wá. Ojuṣe Onigbagbọ́ ni lati pa awọn ofin ilu mọ́ niwọn igba ti wọn ko ba ti lodi si ofin Ọlọrun. A gbọdọ jẹ ẹni ti o n pa Ofin mọ́ ti o si n fi alaafia bá gbogbo eniyan gbé. A ṣe ofin lati jẹ awọn eniyan buburu ni iyà.

**Itẹriba fun Awọn Alaṣẹ**

"Ẹyin ọmọ-ọ̀dọ, ẹ mã tẹriba fun awọn oluwa nyin" (1 Peteru 2:18). Ni ọjọ wọnni, isinru gbilẹ kan, ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe awa ko ni isinru lọjọ oni ni ilẹ wa; a maa n ni ède- aiyede laaarin awọn oṣiṣẹ ati awọn ọga iṣẹ. Awọn aṣẹ wọnyii jẹ mọ́ wọn pẹlu.

A gbọdọ fi ẹsẹ le iṣisẹ Jesu Ẹni ti, nigba ti a kẹgan Rẹ̀ ti ko kẹgan pada. A ki i yin ẹni ti o jiya nitori awọn aṣiṣe rẹ̀, ṣugbọn bi o ba ṣe rere ti o si jiya nitori rẹ̀, eyi lọpẹ.

**Agutan ti o Nù**

Ẹnyin ti nṣako lọ bi agutan, ṣugbọn nisisiyi ẹnyin pada si ọdọ Oluṣọ-agutan ati Biṣọpu ọkàn yin" (1 Peteru 2:25). Awọn ẹlẹṣẹ dabi agutan ti o nù si aginju ẹ̀ṣẹ titi Kristi alaanu Oluṣọ-agutan, fi pe wọn kuro ninu irin-kiri wọn nipa rirán Ihinrere si wọn. O n tọ́ wọn si papa oko tutu ti o dara jù lọ. O si n daabo bo wọn nigba ti wọn ba wa ninu wahala.

**Peteru**

A le fi oju ẹmi wo Peteru ni igba ewe rẹ̀ bi ọdọmọkunrin alagbara, alakinkanju apẹja, ti iru igbesi-ayé ti o n gbé ki i ṣe eyi ti o fa ni mọra. Ṣugbọn lẹyin Pẹntikọsti a le ri i bi alagbara, onigboya, ati alakinkanju ọmọ-ogun Jesu Kristi, ti o le ko ọta loju, ti o si n bá awọn ti o kan Oluwa Ogo mọ́ agbelebu wi.

Ni igba ogbó rẹ̀ a le ri i nipa awọn Episteli rẹ̀ bi baba onifẹ, ti ọkàn rẹ̀ tẹ́: ti ifẹ Jesu ninu ọkàn rẹ̀ ti sọ ọkàn rẹ̀ di rirọ̀ fun awọn ọkàn ti ṣegbe, titi de ibi ti awọn Episteli rẹ̀ ti n sọ ohun ti Ọrun ti o si n gba awọn eniyan mimọ́ niyanju pe ki wọn ki o má ṣe ka idanwo ti ó wà laaarin wọn bi ẹni pe ohun ajeji ni o de ba wọn. Awọn nnkan wọnyii jẹ atẹgun fun igbagbọ́ wọn ti yoo mu ogo wọn pọ̀ sii nigba ifarahàn Jesu Kristi.

Ọrọ iṣiiri rẹ̀ ati imọran rẹ̀ bi a ba tẹle e yoo mu ki olukuluku eniyan mimọ́ ki o "ju aṣẹgun lọ" nipa Jesu Kristi ti o fẹ wọn.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni iwọ rò pé o rú ifẹ Peteru soke lati kọ Episteli yii?

2 Sọ diẹ ninu awọn ihuwasi Peteru.

3 Ṣe alaye bi a ṣe le di mimọ́ ninu ayé yii.

4 Ori ipilẹ wo ni a kọ́ Ihinrere lé?

5 Ki ni ṣe ti a fi n pe Jesu ni "Okuta ãye"?

6 Ki ni iye owo irapada wa?

7 Iru ọkan wo ni wọn ni lati fi gba idanwo wọn?

8 Labẹ Ofin, bawo ni ẹni ti a ti ta nitori gbese rẹ̀ ṣe le di ominira?